**January 2021**

**Agbára Gbọ́dọ̀ pàrọ̀ ọwọ́**

**PÀṢẸ FÚN ỌDÚN**

**ORIN:**

**Ọ̀RỌ̀ AGBÁRA**

1. Àwọn agbára àgbà ìkà, tí a ti yà láti jáyé mi kulẹ̀ ní ọdún yìí, ìdájọ́ ikú máa wá sórí yín lónì ín yìí, ní orúkọ Jésù.
2. Àwọn agbára tí wọ́n fi ayé nimí lára lọ́dún tó kọjá, tí wọ́n sì ti pinnu pé n kò ní rìn jìnnà lọ́dún yìí, iná àrá Ọlọ́run, yóò pa yín run lónì ín, ní orúkọ Jésù.
3. Àwọn ọ̀tá, tí wọ́n ń gbèrò láti kéde ìpọ́njú àti ìrora fún mi lọ́dún yìí, Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí wọn gba ìgbájú ti Áńgẹ́lì lónì ín, ní orúkọ Jésù.
4. Bàbá mi, nípa agbára rẹ lónì ín, jẹ́ kí àwọn ọ̀tá mi ru ẹrù ibi tí wọ́n ti sètò fún mi lọ́dún yìí, ní orúkọ Jésù.
5. Ìdàmú tó ń ṣiṣẹ́ ní òru, ẹ gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, ẹ kò ní gbémi mì lọ́dún yìí, ṣùgbọ́n ẹ máa gbé àwọn ọ̀tá mi mì, ní orúkọ Jésù.
6. Kìnnìún ẹ̀yà Júdà, lọ́dún yìí, fún àwọn ọ̀tá mi ní ìdàmú tí yóò gbé wọn mì, ní orúkọ Jésù.
7. Àwọn agbára, tí a ti yàn láti pa mi kí àlàjá mi tó fara hàn lọ́dún yìí, Ọlọ́run tí ó dójú ti Goliath yóò dójú tìí lónì ín, ní orúkọ Jésù.

**ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ – ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run dìde, kí o sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn, sínú Orí òkè iná àti ìṣẹ́ ìyanu.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé Orí òkè iná àti iṣẹ́ ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Bàbá mi, ìgbàkúùgbà tí mo bá gbàdúrà lọ́dún yìí, jẹ́ kí Goliath olóríkunkun mi ṣègbé nípaṣẹ̀ idà rẹ̀, ní orúkọ Jésù.
4. Ogun ọlọ́jọ́ pípẹ́, tó bá mi jà lọ́dún tó kọjá, n kò ń ṣe tìrẹ lọ́dún yìí, nítorí náà, kú, ní orúkọ Jésù.
5. Agbára ìkà yówù, tí a ti yàn láti máa tẹ̀lé mi káàkiri láti fa ìyọ́nu fún mi lọ́dún yìí, wú kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
6. Agbára yówù, tí ó fẹ́ yí aṣọ ìyìn mi padà sí aṣọ ibojì lọ́dún yìí, kú nípa iná, ní orúkọ Jésù.
7. Àwọn agbára, tí a ti yàn láti ṣiṣẹ́ takun-takun, láti sọ mí di ohun-èlò òfifo lọ́dún yìí, sáré wọ ibojì lọ kí o sì parun, ní orúkọ Jésù.